Àbọ Ìwádìí Tí Ó Rọrun Lórí

# Lílo Ìmọ̀ Ẹrọ Ẹkọ́ Ni Ȧfíríkà:

## Ìkẹ́kọ̀ọ́ Ìfojúsí

BRAIN BUILDERS YOUTH DEVELOPMENT INITIATIVE

GLOBAL CAMPAIGN FOR EDUCATION
www.campaignforeducation.org

## Atọ́ka Àkóónú

Ìsọníṣókí aláṣẹ ..........1
Ìfáárà ..........2
Ìlànà ìwádìí ..........4
Ìdojukọ ìwádìí ..........4
Àwọn ìbéèrè ìwádìí tí ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí ń wá láti dáhùn ..........4
Àkópọ̀ ohun ìwádìí àti àtúpalẹ̀ ..........5
Ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni Afíríkà àti àwọn ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí ìdiwọ̀n ìwádìí ..........6
Níní òye nipa lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni Afíríkà ..........7
Ìtúpalẹ̀ ipò ..........7
Bí wọ́n ṣe ṣe àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ lásìkò àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19 ..........8
Ìmúnádóko ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ lasìkò àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19 ..........10
Ìlọwọ́sí ọmọbìnrin pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni ìhà Ìwọ̀-Oòrùn Sàhárà Afírikà ..........13
Ìwádìí ti Orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ..........13
Ohun ìmúlò iṣẹ́ duró ..........14
Ìkádìí ..........14
Ìwé ìtọ́kasí ..........18


DELL

# *Ìsọníṣókí Aláṣẹ*

Ìwádìí tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ "Lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni Afíríkà ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí" jẹ́ àtẹ̀jáde tí ìpolongo Àgbáyé fún Ẹ̀kọ́ (Global Campaign for Education). Dókítà Ronda Zelezny-Green àti Hannah Metcalfe ni wọ́n kọ ọ́ fún ìpolongo Àgbáyé fún Ẹ̀kọ́ pẹ̀lú àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ àjọṣepọ̀ Jamani, Àjọ Europe, Enabel àti GIZ. Ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí yìí wáyé láti lè lóye bí wọ́n ṣe lọ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni orílẹ̀ èdè méjọ: Botswana, Burundi, Democratic Republic of the Congo (DRC), Madagascar, Malawi, Namibia, Rwanda àti Zambia. Ó ṣe ìdánimọ̀ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́, ìlọ́wọ́sí àwọn iléeṣẹ́ ẹ̀rọ ńlá àti àwọn ìdojúkọ lílọ ìmọ ẹrọ ẹ̀kọ́ lásìkò àjàkálẹ àrùn covid 19. Àbọ ìwádìí tí ó rọrùn yìí ṣe àwárí àwọn ohun tí ó ṣe kókó níbí "Lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni Afíríkà ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí". Èyí láti rí i dájú àwọn ẹ̀kọ́ tí a lè rí kọ́ lára ìwádìí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà èyí tí kò sí lára àwọn  ohun ìmúlò fún iṣẹ́ dúró. Àwọn àwárí fi hàn wí pé kárí ayé títí àwọn iléèwé lásìkò àjàkálẹ̀ Covid 19 jẹ́ kí àwọn àjọ ẹ̀kọ́ ṣe àmúlò oríṣiríṣi ọ̀nà bí i rédíò, amóhùnmáwòrán àti àwọn irinṣẹ́ ayélujára fún ẹ̀kọ́ ọ̀nà jíjìn. Àwọn ọ̀nà yìí yàtọ̀ sí ara wọn ni ìbámu pẹ̀lú orílẹ̀ èdè àti àgbègbè, pàápàá àwọn tí owó kékeré ń wọlé fún. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ẹ̀rí wà nípa ipá tí àwọn iléeṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ńlá kó, láti ṣe ìmúṣẹ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni gbogbo àwọn orílẹ̀ èdè, a ṣe àwárí pé àwọn orílẹ̀ èdè dojúkọ irú àwọn ìtaláyà nígbà ìmúṣẹ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ìgbáradì tí kò múná dóko, íńtánẹ́ẹ̀tì tí kò dára, àìsí ètò fún àwọn ẹ̀kọ́ lórí rédíò, àìní iná, àìsí ìtanijí lórí lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́, àkóónú ìkẹ́kọ̀ọ́ tí kò kún, àìmúnádóko àwọn olùkọ́, àìní ìmúsiṣẹ́pọ̀ tó dára láàrin àwọn àgbègbè àti aládàáni oní ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti àìsí àsọyé lórí ohun ìmúlò. Ìwádìí fi hàn wí pé pẹ̀lú akitiyan ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ gbé lásìkò àrùn Covid 19, ìmúnádóko lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ fún ẹ̀kọ́ ni àwọn orílẹ̀ èdè méjọ kéré. Ó ṣe àfihàn pé àwọn ohun èlò amáyédẹrùn, akẹ́kọ̀ọ́ àti òbí, ìsàkójọpọ̀ àbò, àìsáàbò, òsì, àìbíkìtà àwọn àgbègbè jẹ́ díẹ̀ nínú àwọn ohun tí a nílò láti gbérò láti ṣe ìmúṣẹ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́.




# Ìfáárà

Ni ayé òde òní, ẹ̀kọ́ tí kọjá inú kíláàsì nìkan, ó ti kọjá ẹ̀rọ kọ̀mpútà torí tábìlì tí ó wúwo àti ẹ̀kọ́ tí ó dá lórí ìwé lásán sí ọ̀nà tí ó rọrùn nípasẹ̀ àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ bí i rédíò, amóhùnmáwòrán, àwọn ẹ̀rọ orí ayélujára. Àwọn ohun èlò ojú òpó wẹ́ẹ̀bù, súùmù, ìpàdé gúgù, ojupopo ìdọ́rẹ̀ẹ́, útúbùù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe ń tẹ̀ṣíwájú láti wọ inú ètò ẹ̀kọ́ lágbàáyé, ẹ̀kọ́ kíkọ́ yóò rọrùn púpọ̀, yóò sì wà ni àrọ́wọ́tó. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò kọ́ ẹ̀kọ́ ni ọ̀nà tí yóò rọ kóówá wọn lọ́rùn. Àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ jẹ́ kí ó rọrùn fún àwọn olùkọ́ láti ṣẹ̀dá àwọn ohun ìkẹ́kọ̀ọ́ fún akẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìrírí ẹ̀kọ́ tí yóò ṣe àgbéga àti ìgbéláruge agbára àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti gbogbo àwọn ọmọ iléèwé, láìsí àní-àní ọjọ́ orí wọn tàbí agbára ìkẹ́kọ̀ọ́ wọn. Àìléwu tí ètò ẹ̀kọ́ ni lásìkò pàjáwìrì, ṣẹ̀dá ìyípadà tuntun fún ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ sí ìkẹ́kọ̀ọ́ onílọsíwájú. Ó ń fi ipá mu àwọn ètò ilé-ẹ̀kọ́, àwọn aṣàmì ètò àmúlò àti àwọn olùdókòòwò ètò ẹ̀kọ́ àti àwọn alákòóso ni gbogbo ìpele ètò ẹ̀kọ́ (Ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, girama àti ilé-ẹ̀kọ́ gíga) láti ronú jinlẹ̀ sí ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti àìṣedéédé tí ètò ẹ̀kọ́ ni.

Bí i apákan mìíràn àgbáyé, ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ń ṣẹ̀dá iṣẹ́ àdáṣe tí yóò mu ìrọ̀rùn bá ẹ̀kọ́ àti ìmúdára iṣẹ́ nípasẹ̀ síṣẹ̀dá lílò àti ìṣàkóso àwọn ìlànà ìmọ̀ ẹ̀rọ tí ó yẹ láti túbọ̀ mu ìlọsíwájú bá òye àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ìhà Sàhárà ti Áfíríkà. Nípasẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ ẹ̀rọ ojú mi ló ṣe, ó rọrùn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti ní ìfaramọ́ nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà ìgbádùn ti ẹ̀kọ́. Àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ń pọ̀ sí i gẹ́gẹ́ bí i ohun èlò àkọ́kọ́ fún ìkẹ́kọ̀ọ́ oníjíjìnà ní àwọn àkókò ètò ẹ̀kọ́ pàjáwìrì. Ní pàtàkì, àwọn ìyípadà nínú ètò ọrọ̀-ajé àti ipò òṣèlú ṣẹ̀dá àwọn ààyè fún àwọn ọ̀nà tuntun láti kọ́ ẹ̀kọ́. Bí àpẹẹrẹ, orílẹ̀ èdè Nàìjíríà bẹ̀rẹ̀ ìtọ́nisọ́nà lórí rédíò (Interactive Radio Instruction, IRI) ní ọdún 1992, fún àwọn daran-daran láti túbọ̀ ráyé àti ní àǹfààní sí ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀.

Lẹ́yìn tí àjàkálẹ̀ àrùn Ẹ̀bólà bẹ́ sílẹ̀ ní ọdún 2014, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè Afíríkà tí ó wà ní ìhà Sàhárà pẹ̀lú Democratic Republic of Congo, Liberia, Sierra-Leone àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ló bẹ̀rẹ̀ àwọn ètò ẹ̀kọ́ orí rédíò. Àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19 túbọ̀ jẹ́ kí akitiyan wọ̀nyìí pọ̀ sí i lágbègbè náà.

Ìbádọ́gba sí ìhùwàsí tuntun lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19 jẹ́ ẹ̀rí tí ìmúrasílẹ̀ àti ìrònú sísí. Ọ̀nà tí a kọ́ ẹ̀kọ́, báwo ni a ṣe ń lò pẹ̀lúàwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkọ́, ìtara wà fún àwọn kókó ọ̀rọ̀ kan kì í ṣe ìwọ̀n kan fún gbogbo ipò. Ìpinnu gbogbogboo ni láti ṣe àṣeyọrí ìfojúsọ́nà ìdàgbàsókè alagbero (SDG) 4 èyí tí ó jẹ́ láti rí i dájú wí pé ètò ẹ̀kọ́ tí ó dára, tí ó kún àti déédé àwọn ààyè ìkẹ́kọ̀ọ́ ìgbésí ayé fún gbogbo ènìyàn ní ọdún 2030. Pẹ̀lú pàtàkì ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ láti sàṣeyọrí, ó ń dojúkọ àwọn ìsoòro ìpìlẹ̀ èyí tí bí a kò bá kojú rẹ̀ nípasẹ̀ ìdókòwò tó peye, àti ìfẹ́ òṣèlú, ó lè ṣe ìdíwọ́ ìlọsíwájú tí a ti ṣe tẹ́lẹ̀. Èyí ni pé àwọn àgbáyé ń lọ kúrò ní àwọn ọ̀nà ẹ̀kọ́ àtijọ́. Nítorí náà, ìjábọ̀ yìí ni a fà láti "lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní Afíríkà ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí" àti àwọn ẹ̀kọ́ mìíràn tí ó wà tẹ́lẹ̀ lórí ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ lórí àwọn àwárí kókó, àwọn ẹ̀kọ́ ìwádìí, àti ìwádìí Nàìjíríà tí kò sí lára àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ dúró.



## *Ìlànà Ìwádìí*

Ìwádìí náà ṣe àgbékalẹ̀ ìpìlẹ̀ lórí lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn, tọ́ka sí orílẹ̀ àti ìgbékalẹ̀ ipò orílẹ̀ èdè pẹ̀lú ìdojúkọ pàtó lórí ipò, àwọn àṣà, àwọn agbára, àwọn àìlágbára, àwọn ààyè àti ìrọ́kẹ̀kẹ̀ ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní orílẹ̀ èdè Botswana, Burundi, DRC, Madagascar, Màláwì, Namibia, Rwanda àti Zambia.

### *Ìdojúkọ Ìwádìí*

- Àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ (rédíò, íńtánẹ́ẹ̀tì, ìwé, fóònù alágbèéká, ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) ọ̀nà ìmọ̀ ẹ̀rọ, àwọn amáyédẹrùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí a lò fún ètò ẹ̀kọ́ lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn.

- Àǹfààní ìwọlé sí ìmọ̀ ẹ̀rọ, wíwà àwọn ohun amáyédẹrùn ìmọ̀ ẹ̀rọ, ipò ọrọ̀-ajé, àṣírí dátà, ilé-iṣẹ́ ẹ̀rọ ńlá (Global North, àwọn iléeṣẹ́ tó dá dúró  bí i Microsoft àti Facebook) ìṣọ ẹ̀kọ́ di aládàáni àjọṣepọ̀ aládàáni àti ìjọba, ẹ̀kọ́ àti ìkẹ́kọ̀ọ́, ìkẹ́kọ̀ọ́ olùkọ́, ìríri àwọn akẹ́kọ̀ọ́, ìlọ́wọ́sí àwọn òbí, àyíká ilé, ọ̀rọ̀ àbò àti àwọn aàyè ni a dé. Ó tún ṣe àfihàn ìyapa àwọn orílẹ̀ èdè tí ìwádìí yìí dojúkọ.

- Ẹ̀rí lórí ohun tí ó ṣiṣẹ́ àti ohun tí kò ṣiṣẹ́.

### *Àwọn  Ibéèrè Ìwádìí Tí  Ikẹ́kọ̀ọ́ Ìfojúsí Ń Wá Láti Dáhun*

Ìwádìí náà dáhùn àwọn ìbéèrè ìwádìí mẹ́ta bí a ti sọ ní ìsàlẹ̀.

- Àwọn imoeko wo ni ó wà ní orílẹ̀ èdè náà?
- Báwo ni àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ wọ̀nyìí ti ní ìlọsíwájú tàbí ṣe ìdíwọ́ ẹ̀tọ́ sí ètò ẹ̀kọ́ ní orílẹ̀ èdè náà?
- Àwọn ohun ìmú iṣẹ́ dúró wo ni a lè ṣe? Báwo ni orílẹ̀ èdè ṣe le ṣàmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ láti mu ẹ̀tọ́ sí ètò ẹ̀kọ́ lọ ṣíwájú?

# Àkópọ̀ Ohun Ìwádìí Àti Ìtúpalẹ̀

Ó ṣe pàtàkì láti ní òye bí ìwádìí lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní àwọn orílẹ̀ èdè Afíríkà ṣe wáyé. A gba àkópọ̀ ohun ìwádìí fún oṣù méjì pẹ̀lú àpẹẹrẹ pàtàkì méjì àti àwọn ìlànà ìkójọpọ̀ ohun ìwádìí èèyàn ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò (key Informant (kII) gbígba àkópọ̀ ohun ìwádìí, àti ìwádìí gbígba ohun ìwádìí púpọ̀. Obìnrin àti ọkùnrin mẹ́rìnlá ni a yàn fún ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò náà. Àkókò tí a lò fún àwọn èèyàn tí a fọ̀rọ̀wá-lẹ́nu-wà súnmọ́ ogójì ìṣẹ́jú ní gígùn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò wáyé lórí súùmù (zoom). A lo wọ́saapu (whatsapp) níbi tí àsopọ̀ kò dára. Ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò pẹ̀lú àwọn tó ṣe kókó láti Burundi, DRC àti Madagascar ni a ṣe ní èdè Faranse, àti wí pé a ṣe ìmúṣẹ pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n óni aáyan ògbufọ̀.

Ìwádìí lórí ayélujára ni a tún gbà láti sàkópọ̀ ohun ìwádìí láti ọ̀dọ̀ àwọn olùsọfúnni nípasẹ̀ "Survey Monkey". Ìwádìí náà ní ìbéèrè mẹ́rìnlá, méjìlá jẹ́ oní ìdáhùn tó jẹ́ yíyàn púpọ̀ nígbà tí méjì jẹ́ ìmọ̀ parí ìbéèrè. A ṣe ìwádìí náà ní èdè Faranse àti Gẹ̀ẹ́sì. Ọ̀nà ìsàpẹẹrẹ ìrọ̀rùn (simple Random Sampling, (SRS) ni a pín pẹ̀lú àwọn olùdáhùn nípasẹ̀ ojú ẹ̀rọ ìpolongo Àgbáyé fún ẹ̀kọ́, bákan náà, àtẹ̀jíṣẹ́ oní méèlì sí àwọn kan pàtó tí a mọ̀ pẹ̀lú ìpolongo àgbáyé fún ẹ̀kọ́ àti ẹgbẹ́ ìwádìí. Àwọn ènìyàn yìí ni a gbà wí pé wọ́n jẹ́ amòye ètò ẹ̀kọ́ tí wọ́n sì tún ń ṣiṣẹ́ fún àjọ àwùjọ ará ìlú tí ìpolongo àgbáyé fún ẹ̀kọ́ ṣiṣẹ́ pẹ̀lú.

Àwọn ìlànà ìwádìí tí a gbà láti ẹnu àwọn ènìyàn pàtàkì onífọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò ni a gbèrò láti ojú ọ̀nà àtẹ̀gùn àti Olómìnira. A tún lọ ọgbọ́n ìsọ ìtàn àkọ́ọ́lẹ̀ láti ṣe àfihàn àwọn àwárí láti ìpele ìkójọpọ̀ ohun ìwádìí. A rí i wí pé lílo ìtàn àkọ́ọ́lẹ̀ ṣe pàtàkì nígbà tí ìwádìí onífọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò àti ìwádìí orí ayélujára ni a gbèrò lẹ́gbẹ̀ẹ́ àwọn àwárí tí ó jáde láti inú àtúnyẹ̀wò lítíréṣọ̀. Èyí jẹ́ nítorí àìyàtọ̀ láàrin ohun tí a kọ sínú ìwé ṣaájú Covid 19 nípa bí ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ṣe jẹ́ lílò lákòókò Covid 19 àti ohun tí àwọn ènìyàn tó gbé àwọn orílẹ̀ èdè náà lásìkò àjàkálẹ̀ àrùn ní àwọn orílẹ̀ èdè méjọ tí ìwádìí yìí dojúkọ.



# *Ìmọ Ẹrọ Ẹkọ́ Ní Afíríkà Àti Àwọn Ikẹ́kọọ́ Ìfojúsí Ìdiwọn Ìwádìí*

·A ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Faranse, kì í ṣe ní èdè àwọn olùkópa.

·Ìwádìí naà ni a ṣe látọ̀nà jíjìn nípa lílo àwọn irinṣẹ́ bí i súùmù (zoom) àti wọ́saapù (whatsapp).

Àwọn olùkópa ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò jẹ́ àwọn tó ti ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àjọ ìpolongo àgbáyé fún ẹ̀kọ́.

Olùfitónilétí kan ṣoṣo ni a ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò láti Malawi àti DRC.

Àwọn olùwádìí méjì tí a yàn jẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́ abo. Àwọn méjèèjì jẹ́ ọlọ́làjú.

Àwọn ògbufọ̀ ni a gbáralé láti ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò pẹ̀lú àwọn akópa Faransé. Ní pàtàkì, díẹ̀ lé sí sísọ ju ìtumọ̀ lọ.

# *Bí Wọn Ṣe Ṣe Àmúlò Ìmọ Ẹrọ Ẹkọ́ Laìsiko Àjàkálẹ̀ Àrùn Covid 19*

- Àwọn orílẹ̀ èdè ìhà Sàhárà Afíríkà ṣe àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní ìbámu bí orílẹ̀ èdè kọ̀ọ̀kan ṣe ṣetán, ànfàání ẹ̀kọ́ tí ó wà àti àwọn ìtaláyà.

**Àwárí láti àwárí agbáyé**

- **Lílo ọ̀nà ọlọ́pọ̀:** Àwọn orílẹ̀ èdè lọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ bí i ìmọ̀ ẹ̀rọ rédíò, amóhùnmáwòrán, fóònù, àtẹ̀jíṣẹ́, wọsaapu (Whatsapp) ìpàdé gọ́gù (Google meet) àti súùmù (zoom) àti àwọn iṣẹ́ àmúrelé tó dá lórí ìwé láti lè jẹ́ kí ẹ̀kọ́ tẹ̀ ṣíwájú lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn náà. Àwọn orílẹ̀ èdè bí i Mozambique, Senegal àti Kenya lọ ọ̀nà yìí níbi tí a ti lọ àkójọpọ̀ méjì tàbí mẹ́ta akitiyan láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gba ètò ẹ̀kọ́ lásìkò àjàkálẹ̀ àrùn náà. Orílẹ̀ èdè Mozambique ṣe àkópọ̀ ètò orí amóhùnmáwòrán pẹ̀lú èdè adití àti àkóónú rédíò ní èdè Potuguese àti èdè abínibí, a sì tún pín àwọn ohun èlò tí ó dá lórí ìwé fún ọmọdé láti kàwé fúnra rẹ̀. Ìjọba Senegal àti Kenya sàpapọ̀ amóhùnmáwòrán, rédíò, àti ẹ̀rọ ayélujára. Namibia ṣàmúlò rédíò, amóhùnmáwòrán, ìwé, àtẹ̀jíṣẹ́, ojú òpó ìdọ́rẹ̀ẹ́ fún ìkẹ́kọ̀ọ́ ọ̀nà jíjìn àti àwọn ọ̀nà ìkẹ́kọ̀ọ́ mìíràn tí ìjọba pèsè. (Rodriguez, Cobo, Munoz-Ngar & Sanchez, 2020, Dreesen et al, 2020).
- **Àjọṣepọ̀ gbogbogbò àti aládàáni:** Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ilé-iṣẹ́ aládàáni kó ipa pàtàkì lásìkò títì pa iléèwé nípa ìmúdára àwọn akitiyan ìjọba nípa àwọn àtìlẹ́yìn, wọ́n kò ṣe ìtọ́sọ́nà bí i akitiyan ìtẹ̀síwájú ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Ìgbìyànjú láti tẹ̀ ṣíwájú ìkẹ́kọ̀ọ́ lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn náà jẹ́ ìdarí púpọ̀ láti ọ̀dọ̀ ìjọba. Ipa tí aládàáni máa ń ni òpin ìwọ̀n.
- **Ìlànà ẹ̀kọ́ tó dá lórí ìwé:** Pẹ̀lú títì pa iléèwé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀ èdè ṣe àmúlò ẹ̀kọ́ oníwèé níbi tí wọ́n pín ohun èlò ẹ̀kọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ọ̀nà yìí wúlò ní Botswana, Bunindi, DRC, àti Madagascar, Màláwì, Namibia àti Zambia





# Níní Òye Nípa Lílo Nípa Ìmọ̀ Ẹrọ Ẹ̀kọ́ Ní Afíríkà

Ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ jẹ́ lílo àpapọ̀ ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà, sọfitiwia àti ìlànà ẹ̀kọ́ àti àdáṣe láti jẹ́ kí ẹ̀kọ́ ìrọ̀rùn. Ó ṣẹ̀dá, lò àti ṣàkóso àwọn ìlànà ìmọ̀ ẹ̀rọ àti orísun ètò ẹ̀kọ́ láti ṣe ìrànlọ́wọ́ ìmúdára iṣẹ́ síṣe ètò ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ pẹ̀lú ìsọdọ̀kan àti àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ tuntun fún ètò ìṣàkóso iléèwé tí ó múná dóko àti ìmúnádóko àti àṣeyọrí àwọn afede ètò ẹ̀kọ́. Ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ gba orísìí ọ̀nà láàrin tàbí ìta yàrá ìkàwé, pẹ̀lú àwọn ohun èlò ètò ẹ̀kọ àti eré, àwọn ètò ìṣàkóso ẹ̀kọ́ (LMS) àpéjọ fídíò bí i súùmù (zoom) àti àwọn àpéjọ ìjíròrò lórí ayélujára, rédíò àti àwọn ètò orí amóhùnmáwòrán láti dárúkọ díẹ̀ nínú rẹ̀.

## Ìtúpalẹ̀ Ipò

Àwọn àwárí láti inú ìwádìí orí ayélujára fihàn wí pé títì pa ni DRC, Madagascar, Malawi, Namibia àti Rwanda. Síbẹ̀síbẹ̀, ní Burundi àti Zambia, èyí kò rí bẹ́ẹ̀. Lákòókò tí àwọn iléèwé wà ní títì pa ní àwọn orílẹ̀ èdè wọ̀nyìí, àwọn àwárí ìjábọ̀ náà fi hàn wí pé iléèwé kò sí ní títì pa ní Zambia. Ní Madagascar, àwọn ọmọdé kò ní àǹfààní láti tẹ̀ ṣíwájú ẹ̀kọ́ wọn nígbà tí àwọn iléèwé wà ní pípadé ní àwọn orílẹ̀ èdè mìíràn, ìròyìn náà fi hàn pé àwọn ọmọdé ní àǹfààní láti tẹ̀ ṣíwájú ẹ̀kọ́ wọn nígbà tí àwọn iléèwé wà ní pípadé. Ní DRC, àwọn tí a fi ọ̀rọ̀ wá lẹ́nu wò ní àwọn mọ̀ wí pé ìdá àádọ́rùn-ún (90%) àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ni a gé kúrò níbi ìkọ́ni àti kíkọ́, pẹ̀lú ìdá mẹ́wàá (10%) nìkan tí ó ní àǹfààní láti tẹ̀ ṣíwájú ìkẹ́kọ̀ọ́ ọ̀nà jíjìn.

Ọ̀kan nínú àwọn ipá tí ó ṣe pàtàkì jùlọ, ní ìbámu sí àwọn olùwádìí ni ọ̀gọ̀rọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó pàdánù ìfẹ́ láti tẹ̀ ṣíwájú ètò ẹ̀kọ́ wọn lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n wà ní ilé fún irú ìgbà pípẹ, pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ tí kò padà lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n ṣí iléèwé. Ipa tí pípadé iléèwé ní lórí àwọn ọmọbìnrin jẹ́ ohun ẹ̀rù púpọ̀. Ó hàn gbangba pé nígbà tí àwọn iléèwé ṣí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́, pàápàá àwọn ọmọbìnrin kò padà sílé ìwé. Ìròyìn fi hàn wí pé iye àwọn ọmọbìnrin tó ṣe ìgbéyàwó, lọ sókè, iye pàtàkì àwọn ọmọ obìnrin tí ó gbéyàwó lóyún lákòókò tí iléèwé wà ní títì pa ní DRC.

Ní Màláwì, ìjábọ̀ náà ṣàfihàn pé ṣaájú àjàkálẹ̀ àrùn, ó tó ẹgbẹ̀rún márùn-ún (5,000) ọ̀dọ́ tó ní oyún àìjọjú ní ọdún kan. Ẹ̀wẹ̀, ní oṣù mẹ́jọ láàrin àkọ́kọ́ àti ìgbì kejì Covid 19 ní ọdún 2020. Oyún ọ̀dọ́ ẹgbẹ̀rún márùndínláàádọ́ta ni a jábọ̀. Àwọn olùfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò sọ pé àwọn ìgbéyàwó ẹgbẹ̀rún mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n ọmọdé (25,000) ni a ròyìn láàrin ìgbì àkọ́kọ́ àti ikeji àrùn Covid 19 ní ọdún 2020.

## *Àwọn ìwádìí láti ẹnu àwọn tí wọ́n fọrọ wá-lẹ́nu-wà lórí ojútùú lílo ìmọ̀ ẹrọ ẹkọ́*

- **Burundi:** Àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ni a gbèrò ní Burundi ṣùgbọ́n kò ní ìdàgbàsókè síbẹ̀ ní àkókò tí ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò wáyé.
- **Democratic Republic of Congo:** Ìpilẹ̀ṣẹ̀ tí a ṣe nípasẹ̀ àwọn iléèwé ni DRC láti lo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣe àtìlẹ́yìn ìkẹ́kọ̀ọ́ lákòókò títì pa iléèwé kéré púpọ̀. Ìjọba gbé ohun èlò orí ayélujára kalẹ̀ tí ó ṣe àtìlẹ́yìn ìtẹ̀síwájú ìkẹ́kọ̀ọ́ pẹ̀lú àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ UNICEF. Pẹ̀lú àtìlẹ́yìn yìí, àwọn ẹkọ́ ni a fún ni lórí rédíò àti amóhùnmáwòrán. Ojútùú ẹ̀kọ́ tún wà lórí Vodaeduc àti School Ap níbi tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ní àǹfààní sí ẹ̀kọ́ lọ́fẹ̀ẹ́ nípa lílo ẹ̀rọ ìléwọ́ wọn. Ìpilẹ̀ṣẹ̀ àkọ́kọ́ ni Vodacom DRC sètò . Ó jẹ́ ìpinnu fún àwọn ìdílé tí ó ní àwọn ọmọdé tí wọ́n sì gba àwọn ọmọ náà láàyè, láti lọ orí ayélujára láti mọ irú àwọn ẹ̀kọ́ tí ó wà. Ọ̀pọ̀ náà fún àwọn ìdílé ní àǹfààní láti sọ pọ̀ lórí ìkànnì Vodacom àti wọlé sí àkóónú ètò ẹ̀kọ́. Èkejì ni àsopọ̀ wẹ́ẹ̀bù tí ó pèsè àwọn ohun èlò iléèwé tí ó lè ji kí àwọn ọmọdé dá ṣiṣẹ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé àwọn aládàáni ni ó dábàá ìpilẹ̀ṣẹ̀ náà, ìjọba ni ó wà níbi àmúṣe, nítorí àwọn ìpilẹ̀ṣẹ̀ ní ìdàgbàsókè pẹ̀lú àtìlẹ́yìn àwọn amòye láti ilé-iṣẹ́ ètò ẹ̀kọ́.
- **Madagascar:** A lọ ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán fún àwọn kíláàsì díẹ̀ fún ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti àwọn ènìyàn tó fẹ́ jókòó ṣe ìdánwò ìpele kèje (Grade 7). Ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán jẹ́ ìpìlẹ̀ ètò ẹ̀kọ́ fún àwọn kíláàsì tàárà àti àwọn kíláàsì tí a tàn káàkiri. Gẹ́gẹ́ bí ìjábọ̀ náà, àwọn ìgbé sáfẹ́fẹ́ amóhùnmáwòrán jẹ́ ìpilẹ̀ṣẹ̀ tí ilé-iṣẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀ èdè (MNE).
- **Màláwì:** Lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ lákòókò títì pa iléèwé lásìkò àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19 kéré. Ìjọba ṣe àgbékalẹ̀ ìpìlẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ lórí ayélujára nípasẹ̀ ojú òpó wẹ́ẹ̀bù ìjọba. Èyí nílò dátà láti wọlé àti kò sì ń ṣe ọ̀fẹ́. Nítorí èyí, àwọn ọmọ tí ó wá láti ibi tí kò sówó kòlè wọ ìkànnì ẹ̀kọ́ náà. A tún gbọdọ̀ ṣe àkíyèsí pé ẹ̀rọ rédíò tí ìjọba orílẹ̀ èdè ni wọ́n ń lò fún ẹ̀kọ́ náà.
- **Namibia:** Ìjọba ṣe ìpèsè fún àwọn olùkọ́ láti ní òye fún ẹ̀kọ́ orí ayélujára nígbà àjàkálẹ̀ àrùn. Àfihàn ẹ̀kọ́ orí rédíò àti àkóónú ẹ̀kọ́ nípasẹ̀ lílo ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán ìjọba. Gẹ́gẹ́ bí ìjábọ̀ náà, àwọn ọmọ iléèwé tún ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́ olómìnira bíi Wọ̀saapù (Whatsapp) fún pàsípààrọ̀ ìmọ̀. Àwọn olùkọ́ ṣẹ̀dá àwọn ẹgbẹ́ pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti òbí láti pín àwọn iṣẹ́ ìkẹ́kọ̀ọ́. Níbi tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kò ti ní ẹ̀rọ ìléwọ́, ẹ̀rọ ìléwọ́ ti àwọn òbí ni a ṣàmúlò láti dé ọ̀dọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Wọ́n sọ wí pé ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní Namibia funikekoo jẹ́ okùn ẹ̀mí àti ààlà tuntun fún ìwádìí.
- **Rwanda:** Ẹ̀rọ rédíò àti amóhùnmáwòrán ni a lò fún ètò ẹ̀kọ́ tí ìjọba fọwọ́sí fún ẹ̀kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ìgbìmọ̀ ètò ẹ̀kọ́ Rwanda ṣe ìfilọ́lẹ̀ pẹpẹ orí ayélujára láti gba àwọn ọmọ iléèwé láàyè láti pèsè èsì àti ní àǹfààní sí àwọn ohun èlò ẹ̀kọ́. Àwọn iléèwé díẹ̀ ní àǹfààní láti ṣẹ̀dá iṣẹ́ àmúrelé àti àwọn iṣẹ́ ìyànsílẹ̀ tí a fi ránṣẹ́ pẹ̀lú Wọ̀saapù (Whatsapp) àti àwọn ẹ̀rọ ìdọ́rẹ̀ẹ́ mìíràn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹgbẹ́ ni a ṣẹ̀dá lórí Whatsapp láìṣe fún àwọn ọmọ iléèwé àti olùkọ́. Gẹ́gẹ́ bí ìjábọ̀ náà, Rwanda ṣe àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn oní tẹlifóònù àti olùpèsè íntánẹ́ẹ̀tì fún ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ lórí ayélujára fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. A ṣe àkíyèsí wí pé ìgbìyànjú kí ẹ̀kọ́ tẹ̀ ṣíwájú jẹ́ nípasẹ̀ ìjọba. Àwọn iléèwé aládàáni lo Whatsapp gẹ́gẹ́ bí i pẹpẹ ìkẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn ọmọ ilé-ìwé wọn.

- **Zambia:** Ìjọba ṣe àmúlò rédíò àti amóhùnmáwòrán gẹ́gẹ́ bí i ìkànnì àkọ́kọ́ fún fífún ẹ̀kọ́ onítẹ̀síwájú. Pẹ̀lú àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ àjọṣepọ̀ àgbáyé fún ẹ̀kọ́, àwọn ilé ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ ni a kọ́ ní àwọn àgbègbè Zambia. Èyí fún àwọn olùkọ́ ní àǹfààní láti wọ inú ilé ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ àti bẹ̀rẹ̀ ìkọ́ni ní kíákíá. Àwọn ẹ̀kọ́ náà ni a gbé jáde lórí amóhùnmáwòrán ti ìjọba. Àjọ tó ń rí sí ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́ pèsè ìkànnì kan fún ìkọ́ni tí ó sì padà wà lórí DSTV. Ìjọba tún ṣe àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ilé-iṣẹ́ rédíò olómìnira fún ìgbóhùn sáfẹ́fẹ́ ní àwọn àgbègbè mìíràn.

# Ìmúnádóko Ìmọ̀ Ẹ̀rọ Ẹ̀kọ́ Lásiko Àjàkálẹ̀ Àrùn Covid 19

Ìjábọ̀ náà fi hàn wí pé ìpilẹ̀ṣẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ eléyìkéyìí ní ipa díẹ̀ púpọ̀ lórí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní DRC. Ní pàtàkì, ìdá ọgọ́rin (80%) àwọn olùkópa ṣàlàyé wí pé àwọn kò lóye nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti àwọn ìpilẹ̀ṣẹ̀ tó dá lórí ìwé tí ìjọba ń gbìyànjú láti gbé jáde.

Ní Madagascar, ìjábọ̀ náà fi hàn wí pé ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ kò múná dóko. Èyí jẹ́ bẹ́ẹ̀ nítorí àìní ìmọ̀ nípa lílò rẹ̀. Ó tún fi hàn wí pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn olùgbé ni kò ní àǹfààní sí ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán, rédíò, kọ̀mpútà alágbèéká, kọ̀mpútà, tàbí fóònù alágbèéká. Màláwì ṣe ìmúnádóko pínpín àwọn ohun èlò tí a tẹ̀ jáde ní àwọn apákan orílẹ̀ èdè fún ìlọsíwájú ẹ̀kọ́ ṣùgbọ́n ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ mìíràn dojúkọ àwọn ìtaláyà kan fún wíwọlé. Ní Namibia ìjábọ̀ náà ṣe àkíyèsí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn iléèwé kò ní àǹfààní sí íńtánẹ́ẹ̀tì. Ó ti ṣàfihàn wí pé ìdá ọgọ́ta (60%) ni ó kéré ju kọ̀mpútà ogún. Àwọn iléèwé ní àgbègbè jíjìn kò ní àǹfààní sí íńtánẹ́ẹ̀tì. Èyí kò jẹ́ kí ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ṣe àṣeyọrí nínú àgbègbè náà. A ṣe ìṣirò pé ó kéré jù ìdá ọgbọ̀n (30%) tí àwọn gbìyànjú láti ṣe ìrànlọ́wọ́ tẹ̀ ṣíwájú múná dóko. Òdì kejì ẹ̀wẹ̀, ìjábọ̀ náà fi hàn pé ẹ̀rọ rédíò ni ó wúlò jù ní Zambia. Lápapọ̀, ìmúnádóko ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní àwọn orílẹ̀ èdè méjọ kéré.

# Ìlọ́wọ́sí Àwọn Ìmọ̀ Ẹ̀rọ Ńlá

A ṣe àkíyèsí láti ibi ìjábọ̀ náà wí pé ìlọ́wọ́sí àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ ńlá le ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn aṣètò láti ṣiṣẹ́ takuntakun láti ṣe àmúlò gbogbo irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Wọ́n tún lè ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn orílẹ̀ èdè nípa pípèsè àwọn ohun èlò ìwé oní ìmọ̀ ẹ̀rọ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ìjábọ̀ náà polongo wí pé àwọn òṣèré onímọ̀ ẹ̀rọ ńlá iléeṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ Òkè-Òkun le ṣe ìrànlọ́wọ́ níwọ̀n ìgbà tí wọ́n mọ̀ wí pé nínú ìrírí, lílo ojú òpó ìbánidọ́rẹ̀ẹ́ le jẹ́ kí ètò ẹ̀kọ́ tẹ̀ ṣíwájú fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kan. Bákan náà, àwọn iléeṣẹ́ onímọ̀ ẹ̀rọ ńlá gbọdọ̀ ní ìyànjú láti pèsè àwọn iṣẹ́ dátà kan pàtó fún àwọn ìdí ètò ẹ̀kọ́.

# *Dídá Àwọn Ọrọ  Ètò Mọ̀*

Ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní Afíríkà: Ìkẹ́kọ̀ọ́ ìfojúsí jábọ̀ àwọn ìdánimọ̀ àwọn ìdí púpọ̀ tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ kò ṣe sàṣeyọrí ní ìhà Sàhárà Afíríkà lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19. Ọ̀kan nínú ìwọ̀nyìí jẹ́ ìgbáradì tí kò dára. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé àwọn orílẹ̀ èdè yìí ní àwọn ìgbà sílẹ̀ ìtàn tó jẹ mọ́ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Saájú àjàkálẹ̀ àrùn Covid 19, kò sí ìmúrasílẹ̀ fún ìṣọdọ̀kan ní kíkún sínú ètò ẹ̀kọ́, ní pàtàkì láti ṣe àtìlẹ́yìn fún ìkẹ́kọ̀ọ́.

Pẹ̀lú bẹ́ẹ̀, àsopọ̀ íńtánẹ́ẹ̀tì tí kò dára wà, yàtọ̀ sí Rwanda tó ní ìdá tó pọ̀ jù lílo íńtánẹ́ẹ̀tì àti ohun ìmọ̀ ẹ̀rọ, (pàápàá fóònù alágbèéká) ìdá àádọ́rùn-ún (90%) àti ìdá márùndínlọ́gọ́rin (75%) lẹ́sẹẹsẹ (Ducerte & IMF, 2021) ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè wọ̀nyìí ni íńtánẹ́ẹ̀tì  kò dé. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àwọn àgbègbè ìgbèríko ti gé kúrò ní íńtánẹ́ẹ̀tì nítorí àìráyè sí àwọn amáyédẹrùn alágbèéká tó fún láàyè sí íńtánẹ́ẹ̀tì. Olùkópa ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò ní DRC ròyìn wí pé ìdá àádọ́rin àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ni a gé kúrò pátápátá láti kọ́ni tàbí kọ́ ẹ̀kọ́ pẹ̀lú ìdá mẹ́wàá (10%) (ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú ètò ẹ̀kọ́ kárí ayé aládàáni) ní àǹfààní láti tẹ̀ ṣíwájú ìkẹ́kọ̀ọ́ jíjìnnà. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dojúkọ wàhálà íńtánẹ́ẹ̀tì gíga àti àsopọ̀. Ní Rwanda, ojú òpó wẹ́ẹ̀bù wà fún àwọn tó ní ààyè sí íńtánẹ́ẹ̀tì nìkan. Àwọn olùkópa sétò wí pé ìdá ogójì (40%) àwọn tó wà ní ìlú tí ọ̀làjú wà ló ní àǹfààní, ṣùgbọ́n ó kéré púpọ̀ ní àwọn àgbègbè ìgbèríko ju àwọn àgbègbè ìlú lọ. Íńtánẹ́ẹ̀tì kò ṣe é gbẹ́kẹ̀lé ní gbogbo ìgbà. Ipò yìí kò yàtọ̀ ní Madagascar níbi tí ìdá 19.4% àwọn olùgbé ní àǹfààní sí íńtánẹ́ẹ̀tì (Èèyàn million 5.45) (Kemp, 2021). Ìsòro wà fún àwọn ẹ̀kọ́ tí kò sí ètò fún lórí rédíò. Ní DRC, púpọ̀ nínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kò tẹ̀lé àwọn ẹ̀kọ́ rédíò. Gẹ́gẹ́ bí i ìjábọ̀, kò sétò dáradára. Bákan náà, lílo rédíò àti ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán fún ìkẹ́kọ̀ọ́ kò fi ààyè àti fi èsì ránṣẹ́. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ń gbọ́ ètò ẹ̀kọ́ orí rédíò, wọ́n kàn le gbọ́ ni, wọn kò le fèsì. Nítòótọ́, ó jẹ́ ìrìn ìkẹ́kọ̀ọ́ ọlọ́nà kan fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ní ọ̀nà kan náà, àìní ààyè sí àwọn ìkànnì ìkẹ́kọ̀ọ́ jẹ́ ìsòro ní Màláwì. Níbí, àwọn ọmọ tó wá láti ibi tí wọn kò ti rí jáje kò ní àǹfààní sí àwọn ìkànnì ẹ̀kọ́ nítorí dátà tó gbówó lórí .

Ọ̀rọ̀ àìní iná tún wà ní àwọn ìgbèríko. Ìsòro iná mọ̀nàmọ́ná ni a mọ̀ bí i ìdènà sí ìkópa ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ní àwọn orílẹ̀ èdè mẹ́jọ tí a ti ṣe ìwádìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀ èyí jẹ́ ìgbèríko, àwọn ìsòro yìí tún fi ara hàn ní àgbègbè ìlú tí ọ̀làjú wà. Gẹ́gẹ́ bí i Báǹkì Àgbáyé, agbègbè ìhà Sahara jẹ́ ọ̀kan lara àwọn tó ni iná mọ̀nàmọ́ná tó kéré jù nínú ìdá 48.4% ní àgbáyé ní ọdún 2020. Iná mọ̀nàmọ́ná kékeré ṣe ìdíwọ́ ìdàgbàsókè alagbero, ṣùgbọ́n yóò tún já sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣoro ètò ọrọ̀ ajé.

Ẹ̀wẹ̀, àkóónú ìkẹ́kọ̀ọ́ tí kò ní ètò fi ara hàn gbangba. Ní Màlawi, ìjábọ̀ náà ṣàfihàn pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn kókó ọ̀rọ̀ kò sí nínú ohun èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ lójú òpó wẹ́ẹ̀bù, bí ìbámu sí ìjábọ̀ náà. Àkóónú ètò ẹ̀kọ́ rédíò ìjọba kò ṣe àkíyèsí àwọn ọmọdé tó ní àìlera, bí àpẹẹrẹ, àwọn ọmọdé tó jẹ́ adití àti afọ́jú. Ní Madagascar, àjọ tó ń rí sí ètò ẹ̀kọ́ orílẹ̀ èdè gbìyànjú láti ṣe àwọn kíláàsì nípaṣẹ̀ rédíò àti ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán lórí afẹ́fẹ́, ṣùgbọ́n kò rọrùn nítorí pé ìmọ̀ ẹ̀rọ tí a lò kò ṣe déédé fún àwọn ọmọdé. Gẹ́gẹ́ bí i ìròyìn, àwọn òṣèré eléré ìtàgé ni wọ́n ń lò gẹ́gẹ́ bí i akẹ́kọ̀ọ́ ní yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́.

Ìkósùwọ̀n àwọn olùkọ́ lórí ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Ní àfikún, àwọn olùkọ́ ní iléèwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti girama àti pàápàá, ilé-ẹ̀kọ́ gíga kò lè rí i dájú wí pé ẹ̀kọ́ tẹ̀síwájú nípa lílo àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Yàtọ̀ sí àìní ọgbọ́n lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ àwọn olùkọ́, ìjọba àti àwọn òṣèré pàtàkì ètò ẹ̀kọ́ kò ní ìpèsè láti ṣe àgbékalẹ̀ àti gbé jáde àkóónú ẹ̀kọ́ orí ayélujára.


Ní Botswana, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùkọ́ kò ní ẹ̀kọ́ tàbí ìrírí pẹ̀lú ẹ̀kọ́ àti ìkẹ́kọ̀ọ́ àtọ̀nà jíjìn. Àìní ìbáṣepọ̀ ìmúṣiṣẹ́pọ̀ láàrín àwọn gbogbo ènìyàn àti aládàáni, àwọn akitiyan ìsọdọ̀kan wọn kéré.

Láàrín ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn tó ní í ṣe pàtàkì láti ṣe ìgbélẹ́wọ̀n ìwúlò nigbati àjàkálẹ̀ àrùn COVID-19 bẹ́ sílẹ̀ láti ṣe ọ̀nà pípé láti kojú ìwúlò àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n bá ara wọn nílé láìròtẹ́lẹ̀. Nítorí náà, àwọn olùkọ́ni, àwọn akẹ́kọ̀ọ́, àti àwọn òṣèré díẹ̀ fún ìmúlò rí àjàkálẹ̀ àrùn náà bí i àyè láti má ṣe ohunkóhun.

Àìsí ètò ìmúlò fún ìlò ìmọ̀ ẹ̀kọ́ tún jẹ́ ohun ìbàjẹ́ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìpínlẹ̀, pàápàá fún irú àkókò báyìí. Bí àpẹẹrẹ, àkóónú ètò ẹ̀kọ́ fún gbogbo iṣẹ́ àwọn alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, girama àti àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga kọ̀ọ̀kan kò wà fún ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́. Nítorí náà, ó nira púpọ̀ fún àwọn ọmọdé láti kọ́ ẹ̀kọ́ fún ìgbà àkọ́kọ́ ní ìgbésí ayé wọn láì rí àwọn olùkọ́ wọn tàbí láti lọ sórí ayélujára láti wọlé sí àwọn ohun èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ dípò ọ̀nà kíkọ sílẹ̀. Ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, àti àwọn orílẹ̀ èdè mìíràn ní ìhà Sahara, ó jẹ́ ohun tí ó nira fún àwọn ọmọdé láti faramọ́lé àṣà tuntun yìí. Èyí jẹ́ pàápàá fún àwọn ọmọdé tí kò tí ì ní àǹfààní sí ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ rí.

## *Àpótí kin-ín-ní: Ohun àmúlò láti ṣe àkíyèsí nígbà tí a bá ń ṣe ìmúṣẹ ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́.*

- Àbò àwọn ọmọdé
- Ìfáradà owó íntánẹ́ẹ̀tì
- Ìpele òṣì
- Ìyàtọ̀ agbègbè
- Àǹfààní sí ìmọ̀ ẹ̀rọ
- Ìpele ìmọ̀wé àwọn olùkọ́ nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ: Àwọn olùkọ́ gbọdọ̀ ní òye ìmọ̀ ẹ̀rọ. Wọ́n tún gbọdọ̀ gba ìkẹ́kọ̀ọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ sí i láti lè jẹ́ kí wọ́n ní agbára láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́.
- Wíwá ètò ìmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti ìpele ìmúṣẹ.
- Ìdókoòwò ti ilu àti aládàáni lọ́wọ́ lọ́wọ́ nínú ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti wíwà àwọn ohun èlò.
- Òye àwọn òbí nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ.
- Ohun èlò amáyédẹrùn.
- Àjálù àdáyébá, àjàkálẹ̀ àrùn mìíràn, rògbòdìyàn àti ojú ọjọ́ tó gajù le jású títìpa iléèwé púpọ̀.
- Ọ̀rọ̀ akọ/abo.



# Ìlọ́wọ́sí Ọmọbìnrin Pẹlú Ìmọ̀ẹrọ Ẹkọ́ Ní Ìhà Sahara Ti Áfíríkà

Àwọn obìnrin àti àwọn ọmọ obìnrin tẹ̀síwájú láti wa ní ìyàsọ́tọ̀ púpọ̀ jùlọ àti àwọn ènìyàn tó wà nínú ewu lákòókò àwọn pàjáwìrì ìleera bí i COVID-19. Àwọn ìjábọ̀ ìsáájú tó ní í ṣe pẹ̀lú rògbòdìyàn pàjáwìrì tọ́ka sí wí pé ìbẹ́sílẹ̀ aburú kún àìlágbára tí ó wà tẹ́lẹ̀ tí àwọn ọmọ obìnrin àti obìnrin. Ó ṣẹ̀dá àwọn tuntun àti pé ó ń ṣe àfikún àìdọ́gba abo tó wà láwùjọ (UNFPA, 2020, King & World Vision, 2020). A lè ṣe àkíyèsí ní gbogbo àwọn orílẹ̀ èdè tí a ti ṣe ìwádìí pé pípàdé iléèwé kan àwọn ọmọbìnrin. Gẹ́gẹ́ bí i ìjábọ̀ náà, ìlọsókè wà níbi ìgbéyàwó ọmọdé àti oyún ọ̀dọ́. Àwọn òbí tún kọ̀ láti fi àwọn ọmọ wọn ránṣẹ́ sí iléèwé nítorí italaya owó. "Tí a bá ní láti sọ ẹ̀kọ́ orí ayélujára di pàtàkì lọ́jọ́ iwaju, ẹ̀kọ́ àti àkíyèsí gbọdọ̀ wà fún àwọn obinrn lórí bí wọ́n ṣe le lo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ láì sí ewu." Ní Zambia, Ìpolongo fún Ẹ̀kọ́ àwọn Obìnrin (CAMFED) ṣe àmúlò Wọ́saapù (Whatsapp), ìpàdé gúgù (Google meet) àti súùmù (zoom) láti ṣe àbẹ̀wò àlàáfíà lórí àwọn ọmọbìnrin ìkànnì wọn àti láti dẹrọ̀ ìfijíṣẹ́ ìkẹ́kọ̀ọ́, níbi tí ó ti ṣe é ṣe. (FHI360, 2021).

Yàtọ̀ sí àwọn akitiyan CAMFED ní Zambia, kò sí ètò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ tí a mọ̀ ní pàtó fún àwọn ọmọbìnrin àti obìnrin nínú ìjábọ̀ wa. Ní pàtàkì púpọ̀ jùlọ àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ kì í ṣe ìfarabalẹ̀ fún abo. Ìlànà ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ tó ní ìmọ̀lára abo jẹ́ bọ́tìnì jẹ́ ìdánilójú ìtẹ̀síwájú àwọn ọmọbìnrin àti ìforúkọsílẹ̀ ní iléèwé lákòókò pàjáwìrì ìlera tàbí àwọn àdálù àdáyébá mìíràn tí ó lágbára láti fa iléèwé títì pa.

## Ìwádìí Orílẹ̀ Èdè Nàìjíríà

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé orílẹ̀ èdè Nàìjíríà kọ́ ni ìdojúkọ nínú ìjábọ̀ náà, ẹ̀rí fihàn wí pé Nàìjíríà, nípasẹ̀ àjọ àpapọ̀ tó ń rísí ètò ẹ̀kọ́ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà àti ìgbìmọ̀ rẹ̀, àjọ tó ń rísi ètò ẹ̀kọ́ kárí ayé ti bẹ̀rẹ̀ Ẹgbẹ́ Ìdáhùn Ìṣọ̀kan fún Ẹ̀kọ́ oní ètò ilé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó tó mílíọ̀nù ogójì, ìdá ọkàn-lé-láàdọ́rùn-ún (91%) tí ó wà ní iléèwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti girama, àti mílíọ̀nù mẹ́wàá àbọ̀ (10.5M) tí àwọn ọmọdé orílẹ̀ èdè tí ó wà ní ọdún márùn-ún sí mẹ́rìnlá (UNESCO, 2020) (FMoE, 2020). Ní ìpele ìjọba àpapọ̀, kọ́ Ẹ̀kọ́ Nílé ẹ̀dá Ọ̀nà ìkẹ́kọ̀ọ́ méjì lórí ayélujára, schoolgate.ng and mobile classroom.com.ng, èyí tí, pẹ̀lú àjọṣepọ̀ UNESCO ṣẹ̀dá ìpìlẹ̀ kan tí wọ́n ń pè ní "School Meet the Learner Approach". Akẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfààní lórí oríṣiríṣìí òpó bíi rédíò, amóhùnmáwòrán, àti Utubù (You Tube).



# *Àpótí Kejì: Àwọn ẹ̀rí mìíràn lórí ìgbìyànjú lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́*

**Npower Tech Edtech Intiative:** Ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ kì í ṣe ohun tuntun ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ní ọdún 2017, ìjọba àpapọ̀ pín ẹgbẹẹgbẹ̀rẹún àwọn tábúlẹ̀tì (Npower Tech Tablets) Afnone Zin I, Speed wondow, Zinox Zpad, Tecno pad, Samsung Idoe E, Rig àti Floss signature tablets) pẹ̀lú àwọn ohun èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ fún gbogbo ìkẹ́kọ̀ọ́. Ẹ̀yí jẹ́ ti olùkọ́ nìkan, akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkọ́ tí kì í ṣe Npower ní iléèwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti girama kò sí lára àwọn tó jẹ àǹfààní.

Rédíò àwọn darandaran tó wà fún ètò ẹ̀kọ́ (Nomadic Interactive Radio Instruction (IRI): Níbí, àwọn ẹgbẹ́ ìgbóràn rédíò di di dídásílẹ̀ tí wọ́n sì ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìkẹ́kọ̀ọ́ alágbèéká. Ó bẹ̀rẹ̀ ní ọdún 1992 láti mú ìlọsíwájú bá ìforúkọ sílẹ̀ àwọn ọmọ iléèwé pọ̀ sí i. Ní ọdún 1996, "Federal Radio Cooperation" tí Nàìjíríà ní Kaduna fún ẹ̀ka ètò ẹ̀kọ́ ní ọgbọ̀n ìṣẹ́jú lórí afẹ́fẹ́ èyí tí ó gbé ìwé ìròyìn kan tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ "Don Makiyaya a Ruga" (Fún àwọn darandaran ní ibùgbé wọn). Ẹ̀tò orí rédíò náà jẹ́ èyí tí wọ́n lè kópa. Àwọn ẹgbẹ́ olùtẹ́tísí ètò wọn yóò sì fi ìdáhùn ránṣẹ́ nípa lílo ẹ̀rọ èsì tí a sètò láti jẹ́ kí ètò náà múná dóko. Lẹ́yìn náà, ètò ẹ̀kọ́ rédíò fún ẹ̀yà àwọn àgbà (Adult Component of Interactive Radio Instruction (IRI) ni wọ́n ṣe ní ọdún 2000, èyí tí ètò mẹ́tàlá wáyé. Gbogbo àwọn ètò náà ní a gbé jáde sí àwọn ẹgbẹ́ olùgbọ́rọ̀ rédíò, tí a gbà bí i ilé iṣẹ́ ìkẹ́kọ̀ọ́ ní ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìpínlẹ̀ mẹ́rìn-dín-lógójì àti olú ìlá orílẹ̀ èdè tó wà ní Àbújá. Gẹ́gẹ́ bí àjọ UNESCO (2016) ṣe sọ, àṣeyọrí tí ìkẹ́kọ̀ọ́ àwọn àgbà ti ètò ibi yọrísí ìfilọ́lẹ̀ ètò iléeṣẹ́ tí ó dá lórí ìwé, ní South Africa nípasẹ̀ "Opening Learning Systems Education Trust (LSET).

**Edo-Best@Home:** Ẹ̀tò Ìpìlẹ̀ Ẹ̀kọ́ tí ìpínlẹ̀ Ẹdó (Edó BEST) mú ìlọsíwájú fún àbájáde ìkẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn ọmọdé tó ju ẹgbẹ̀rún lé lọ́ọ̀dúnrún, o dín àádọ́ta káàkiri àwọn iléèwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tó lé ní ẹgbẹ̀rin ní ìpínlẹ̀ Ẹdó lórílẹ̀ èdè Nàìjíríà sáájú àjàkálẹ̀ àrùn COVID 19. Lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn, ìpínlẹ̀ Ẹdo ṣe ìfilọ́lẹ̀ Edo Best@Home, àjọṣepọ̀ gbogbogbo-aládani láàrín ìpínlẹ̀ Edó, Báǹkì Àgbáyé, Ilé ẹ̀kọ́ gíga Bridge (Bridge International Academies). Ìpilẹ̀sẹ̀ náà pèsè ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ látọ̀nà jíjìn orí ayélujára ní kíkún tí a lè ní àǹfààní láti wọlé nípa lílo ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà tàbí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká, èyí tí àwọn ìkẹ́kọ̀ọ́ aláfetí gbọ́ wà, ìwé itan lórí ẹ̀rọ wẹ́ẹ̀bù, ìbéèrè ìbánisọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ alágbèéká, àti àwọn yàrá ìkàwé orí ẹ̀rọ. Lábẹ́ ètò náà, ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ tó ti wà tẹ́lẹ̀ fún àwọn olùkọ́ túnbọ̀ rinlẹ̀ si i, wọ́n sì sàmúlò rẹ̀ fún ìkẹ́kọ̀ọ́ ọlọ́nà jíjìn. Àwọn olùkọ́ni ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn olùkọ́ lákòókò tí wọ́n ń lo Edo-BEST@Home àti yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ orí afẹ́fẹ́. Àwọn olùkọ́ le dáhùn ìbéèrè àwọn ọmọ iléèwé nípasẹ̀ àwọn yàrá ìkàwé orí afẹ́fẹ́, bákan náà, wọ́n lè fèsì sí iṣẹ́ àmúrelé àti ìbánisọ̀rọ̀ pẹ̀lú akẹ́kọ̀ọ́ àti òbí nípasẹ̀ pípè lórí fóònù, àtẹ̀jíṣẹ́ àti Wọ́sapù (Whatsapp) (Banki Àgbáyé 2021)

**Iṣẹ́ àkànṣe AGILE:** AGILE dúró fún "Adolescent Girls Initiative for Learning and Empowerment Project". Ó jẹ́ iṣẹ́ àkànṣe oní ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta mílíọ̀nù ìrànlọ́wọ́ tí Báǹkì Àgbáyé gbà lérò láti mú ìlọsíwájú àwọn àǹfààní ètò ẹ̀kọ́ girama láàrín àwọn ọmọbìnrin ní àwọn agbègbè tí a fojúsí ní àwọn ìpínlẹ̀ tí ó kópa (Katsina, Kano, Kebbi, Zamfara, Jigawa, Sokoto àti ìpínlẹ̀ Borno). Wọ́n fọwọ́ sí i ní ọdún 2020 lákòókò COVID 19 pẹ̀lú àkókò ìmúṣẹ ọdún márùn-ún (2021-2025). Iṣẹ́ àkànṣe náà ní irinṣẹ́ mẹ́ta:

1. Ẹ̀yà àkọ́kọ́, Ṣíṣẹ̀dá àyè àìléwu àti àyè ìkẹ́kọ̀ọ́ wọlé.
2. Ṣíṣe idagbasoke agbègbè fún àwọn ọmọ obìnrin.
3. Ìṣàkóso iṣẹ́ àti ìmójútó àwọn ètò (Báǹkì Àgbáyé 2020).

Lábẹ́ ẹ̀ka kejì, ìrètí wà wí pé wọ́n ró àwọn ọmọbìnrin lágbára pẹ̀lú àwọn ọgbọ́n ìgbésí ayé tó ṣe pàtàkì fún lílò tágbà bádé àti fún ìmọ̀ ẹ̀rọ. Àwọn iṣẹ́ náà ní í ṣe pẹ̀lú níní ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ àti pẹpẹ ìkẹ́kọ̀ọ́ láti ọ̀nà jíjìn.

Ìkẹ́kọ̀ọ́ ìmọ̀wé ẹlẹ́rọ yóò pèsè àwọn ọmọ iléèwé pẹ̀lú ọgbọ́n ìmọ̀wé orí ẹ̀rọ àti ìmọ̀ tí ó pẹ̀lú:

(a) Lílo ẹ̀rọ ìléwọ́ alágbèéká oní nọ́ḿbà.

(b) Wíwá, rírí, ní àǹfààní àti rírọ̀jinlẹ̀ àwọn ohun tí a rí lójú òpó wẹ́ẹ̀bù.

(c) Ṣíṣe àṣeyọrí lórí lílọ kiri lórí òpó aláìní nọ́ḿbà.

(d) Kíkọ, kíkà àti yíyọ àlàyé níbi ohun wíwò àti ohùn gbígbọ́.

(e) Ṣíṣẹ̀dá àwọn àbájáde ìkẹ́kọ̀ọ́ tuntun nípa lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ.

(f) Wíwọlé sí àkóónú lórí ayélujára, àti

(g) Ìbáṣepọ̀ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀.

Ìpèsè ààbò lórí ayélujára yóò wà láti ṣe ìdíwọ́ fún àwọn ọ̀dọ́ láti wùwà apanirun àti ìlòkulò. Yóò wà lórí àwọn tábúlẹ̀ẹ̀tì (tablets) àti àwọn ohun èlò tí ó yẹ fún àsopọ̀ íntánẹ́ẹ̀tì. Ìrètí wà pé àwọn ọmọ iléèwé yóò gba, ó kéré jù, wákàtí méjì sí mẹ́ta ìkẹ́kọ̀ọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ lọ́sọ̀ọ̀ṣẹ̀. (World Bank, 2020).

Lónìí, ìpín fúnni ìsúná fún iṣẹ́ àkànṣe AGILE ti lé sí i láti bílíọ̀nù mẹ́ta lé láàdọ́ta nínú ìsirò ìsúná ọdún 2023 ti ìjọba Àpapọ̀ Nàìjíríà ń gbèrò.

Ní ìpele ti ìpínlẹ̀, ẹ̀kọ́ tí ó pọ̀ sí i wà nípaṣẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ orí ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán àti rédíò, ní ìbámu pẹ̀lú ètò ẹ̀kọ́ girama, ó sì fa ìwúrí láti ọ̀dọ̀ àwọn ajọ tíkò rọ̀gbọ̀kú lé ìjọba àti àjọ aládàáni. Die nínú àwọn àjọ tí kò rọ̀gbọ̀kú lé ìjọba àti àwọn òṣèré aládàáni bí i Ulesson àti Teach for Nigeria sakitiyan pẹ̀lú pípèsè ẹ̀kọ́ ìróni lágbára fún àwọn olùkọ́ àti bíbẹ̀rẹ̀ ètò ìdàgbàsókè amáyédẹrùn láti jẹ́ kí ẹ̀kọ́ orí ẹ̀rọ rọjú, Ulesson ní pàtàkì ṣẹ̀dá ìpìlẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ olówó kékeré lórí àwọn ẹ̀rọ alámùlọ́wọ́ tí ó dojúkọ iṣẹ́ sáyẹ́ǹsì fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ girama kékeré.

## *Ohun Ìmúṣe Iṣẹ́ Dúró*

- Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn olùkọ́ lórí bí wọ́n ṣe lè lo àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ní yàrá ìkàwé. Èyí yẹ kí ó jẹ́ ìlànà tí ó tẹ̀síwájú àti wí pé ó yẹ kí ó dàpọ̀ mọ́ ìkẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n olùkọ́.
- Ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ jẹ́ èyí tí ó gbèrò láti ṣe àtìlẹyìn fún ìkẹ́kọ̀ọ́, yálà àjàkálẹ̀ àrùn wà tàbí kò sí. Èyí yóò ṣẹ̀dá ìmọ̀ faramọ́lé fún àwọn ìjọba, olùkọ́, àti akẹ́kọ̀ọ́. Àwọn iléèwé gbọdọ̀ ṣàmúlò ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ nínú iṣẹ́ kílàásì wọn lóòrè kóòrè.
- Bí iná mọ̀nàmọ́ná ṣe ṣe pàtàkì, kí ìjọba ṣe ìwúrí fún lílo agbara òòrùn ní àwọn iléèwé bí ọ̀nà ìpèsè agbara mìíràn, paapaa ní àwọn agbègbè tí ó nira láti dé tí iná mọ̀nàmọ́ná kò sí. Kí àtìlẹyìn wà fún èyí pẹ̀lú àwọn irinṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ bí i tábúlẹ̀ẹ̀tì (tablets). Tábúlẹ̀ẹ̀tì (tablets) fún akẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ṣe é ṣe, àti wí pé ó lè jẹ́ ọ̀nà kan láti kojú ìyapa ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ tí ó wà ní iléèwé.
- Kí àwọn ìpolongo ìtanijí wà, àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àti àwọn àkókò àlàyé láti ṣe ìrànlọ́wọ́ láti ṣe àwọn ètò tó jẹ́ mọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́
- Àyẹ̀wò ṣe pàtàkì láti lè lóye apákan wo orílẹ̀ èdè ni ó ti ní ìmúṣe ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ àti èyí tó ń tiraka. Èyí ṣe pàtàkì láti le yanjú àti lànfàání ètò ìmúlò dídásí.
- Yíyọ owó orí kúrò láti ara àwọn ẹ̀rọ bí i kọ̀ǹpútà alágbèéká, kọ̀ǹpútà tábìlì, ẹ̀rọ ìléwọ́, fún ìlò ìmọ̀ ẹ̀kọ́ láti ṣe àṣeyọrí nítorí ó ṣe faradà, ó sì jẹ́ ìdánimọ̀ fún ìdárasí ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ ní ìha Sàhárà ti Áfíríkà.
- Kí ìjọba lájọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn olùpèsè íntánẹ́ẹ̀tì láti pèsè àwọn ìdì dátà ọ̀fẹ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti ní àǹfààní wíwọlé sí àwọn ẹ̀kọ́ orí ayélujára.
- Ṣe àfihàn àwọn ẹ̀kọ́ ICT sí àkóónú ètò ẹ̀kọ́ láti ṣe àtìlẹyìn fún ìkẹ́kọ̀ọ́ jìnà-jìnà.
- Fífi kún àwọn akitiyan láti ṣe àtúnṣe ètò ìmúlò àti àwọn ìlànà láti lè jẹ́ kí ìráyè gbohùngbohùn túnbọ̀ ṣe é faradà, níní àǹfààní ìwọlé, àti ìwúlò gbogbo àgbáyé láti wà pẹ̀lú ìdàgbàsókè ọgbọ́n, láti lo àwọn ìlọsíwájú ìmọ̀ ẹ̀rọ ní kíkún (Alper & Miktus, 2019).

## *Ìkádìí*

Ìwádìí yii ṣe ìrànlọ́wọ́ láti fi hàn pé ipa tí ìmọ̀ ẹ̀rọ kó lórí àwọn iléèwé, kíkọ́ àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ti dínkù gidi ní Botswana/ Burundi. DRC, Madagascar, Màláwì, Namibia, Rwanda àti Zambia, bákan náà níbi ìwádìí Nigeria. Lákòókò àjàkálẹ̀ àrùn náà, àìní ìkẹ́kọ̀ọ́ ọlọ́nà jíjìn àti àìsí àyè láti kópa nínú àwọn ìkẹ́kọ̀ọ́ nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ, nigba àti níbi tí wọ́n ti nílòò rẹ̀, láìbìkítà ipò ara ẹni, di ti àgbáyé. Ní ọ̀nà, àwọn sábàbí yii ṣiṣẹ́ bí ọ̀nà láti fi ipá mú àwọn ìjọba, ní pàtàkì, àwọn orílẹ̀ èdè tó wà ní ìhà Sahara ti Áfíríkà láti bẹ̀rẹ̀ ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ dé ilé-ẹ̀kọ́ gíga le tẹ̀síwájú ẹ̀kọ́ wọn. Pẹ̀lú ìgbìyànjú àwọn orílẹ̀ èdè yii láti pèsè ètò ẹ̀kọ́ tó dára fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn, nípaṣẹ̀ àjọṣepọ̀ gbogbogbo àti aládàáni àti italaya ọ̀nà ìkẹ́kọ̀ọ́ tó dá lórí ìwé tún ṣe àfihàn ìdíwọ́ iṣẹ́. Ẹ̀rí láti inú ìwádìí yìí fi hàn wí pé fún nílo ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ láti ṣiṣẹ́ kíkún ní àwọn orílẹ̀ èdè wọ̀nyìí, ó ṣe pàtàkì fún ìjọba láti ṣe àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn tí ó ní í ṣe pàtàkì láti mú ìlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ẹ̀kọ́ sí ìmúṣe láti mú àṣeyọrí bá ìfojúsọ́nà ìdàgbàsókè alágbéro (SDG4).



## *Ìwé Ìtọ́kasí*

Akash Khemka. (2021). What Is Edtech, https://www.scribd.com/document/502721509/What-is-EDtech

Alper, C. E., & Miktus, M. (2019). MF Working Paper African Department Digital Connectivity in Sub-Saharan Africa: A Comparative Perspective 1. IMF. https://www.imf.org/-/media/Files/Publications/WP/2019/wpiea2019210-print-pdf.ashx

Alberto Muñoz-Najar et. al. (2021). REMOTE LEARNING DURING COVID-19: Lessons from Today, Principles for Tomorrow. Publication of International Bank for Reconstruction and Development / The World Bank, https://www.worldbank.org/en/events/2021/11/11/remote-learning-during-covid-19-lessons-from-today-principles-for-tomorrow

Electricity Access in Sub-Saharan Africa:: World Bank Report, https://openknowledge.worldbank.org/bitstream/handle/10986/31333/9781464813610.pdf?sequence=6&isAllowed=y

Global Digital Right, ttps://datareportal.com/search?q=zambia

"Harnessing EdTech in Africa: Scoping Study", A Publication of Global Campaign for Education (GCE) 2022

FGN Approved 2022 and Proposed 2023 Budget Estimates, Budget Office of the Federation.

Helena Lazero (N/A). What is EdTech and Why Should it matter to you? https://generalassemb.ly/blog/what-is-edtech/

Inclusive Internet Index 2022, https://impact.economist.com/projects/inclusive-internet-index/2022/country/Nigeria

Kgosi Motshabi. (2020). Lessons from Botswana on Continuing Learner Engagement During Covid-19, https://www.reach.gse.harvard.edu/blogs/covid-19/series/lessons-from-botswana-on-continuing-learner-engagement-during-covid-19

Lisa Hartenberger-Toby. (2020). Lessons Learned about Remote Learning from Liberia's Ebola Crisis, https://www.edc.org/blog/lessons-learned-about-remote-learning-liberias-ebola-crisis

UNESCO. (2016). Use of Radio in a Nomadic Education Programme, Nigeria, Retrieved from https://uil.unesco.org/case-study/effective-practices-database-litbase-0/use-radio-nomadic-education-programme-nigeria

Intrerbet Socet The Internet Society Pledges to Expand Internet Access in Africa, https://www.internetsociety.org/news/press-releases/2022/the-internet-society-pledges-to-expand-internet-access-in-africa/

UNESCO. A Bayesian Cohort Model for Estimating SDG Indicator 4.1.4: Out-of-School Rates, https://www.unesco.org/gem-report/sites/default/files/medias/fichiers/2022/08/OOS_Proposal.pdf

UNESCO. (September 2022) New estimation confirms out-of-school population is growing in sub-Saharan Africa, FACTSHEET 62 / POLICY PAPER 48, https://unesdoc.unesco.org/ark:/48223/pf0000382577



**BRAIN BUILDERS**
YOUTH DEVELOPMENT
INITIATIVE